# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸ́LẸ̀

## ODÒ ÌYÈ KAN

## Ìtàn ...

**2 Awọn Ọba 5:1-4**

Naamani jẹ́ akíkanjú, ọlọ́rọ̀, o si jẹ́ olókìkí ati alaṣẹ olórí ogun Siria, ṣùgbọ́n ó dẹ́tẹ̀, àìsàn tí ó burújù ni ìgbà Bibeli ni ẹ̀tẹ̀. Ẹ̀tẹ̀ túmọ̀ sí yíya ènìyàn kurò laarin àwọn olólùfẹ́ fún ìgbà pípẹ́, tí o yẹ sí ikú. Ẹrú binrin Heberu kan to nsiṣẹ ni ilé Naamani lo sọ wípé bi ọ̀gá oun ba le e lọ sí ọ̀dọ̀ woli Elisa ni Israeli, pé yio wo Naamani sàn ninu ẹ̀tẹ̀ rẹ́.

Níwọ̀nba ìgbà tí o jẹ́ wipe irètí ọ̀nà abayọ ni Naamani nwá, o gbéra lọ si Israeli bí ó ti jìnà tó nì. O si tún mú awọn ẹgbẹ́ ọmọ-ogun ajija-gbara, owó ati ohun èlò ti yio fi san owó ìwòsàn rẹ dani pẹlu rẹ̀. Nigbatí Naamani dé iwájú ilé woli náà, Elisa kò jade si i. Dípò ki Elisa jade si Naamani, o rán iranṣẹ kan si i pẹlu aṣẹ pé: "Lọ, ki o si wẹ̀ ni Jordani nígbà meje, ẹran-ara rẹ yio si tún pada bọ̀ si ipò fun ọ, iwọ o si mọ́." 2 Awọn Ọba 5:10.



Woli pàṣẹ ki Naamani lọ wẹ̀, èyí tumọ̀ si wípé Naamani dọ̀tí! Pé kí o lọ wẹ̀ ni ìgbà meje - ninu omi ẹrọ̀fọ̀, jẹ́ iṛẹsilẹ̀ fun Olori ogun ọba Siria ti o jẹ́ onigberaga yi. Pẹlú ìrunú, Naamani yi ẹsin rẹ pada lati lọ sí ilé. Ṣugọ́n kí ó tó dé Damasku, Naamani yio gba ẹ̀gbẹ́ odò Jordani kọja. Bi o ti nkọjá lọ, ọmọ ọ̀dọ̀ Naamani bẹ̀ ẹ́ pé kí o gbìyànjú lati tẹle ìmọ̀ràn woli náà. O sì dá ẹsin dúró, o sokàlẹ̀, o bọ ihamọra rẹ̀ kúrò lọ̀rùn, èyí tí o bo ẹ̀tẹ̀ rẹ. Naamani sì sọ̀kalẹ̀ sinu odo Jordani. Ni ìgbà mẹ́fà, o wọnu odò, ko si àbájade kankan, ṣùgbọ́n nigbatí o jáde wá ni ìgbà keje, ẹ̀tẹ̀ náà ti lọ! Ẹran ara rẹ̀ si mọ́, o sì tún ní ìlera gẹ́gẹ́ bi ti ọmọ kékeré.

Gẹ́gẹ́ bi Naamani ṣse ri ìmúpadàbọ̀sípò, ìwọ pẹ̀lú le ní ìrírí ìwòsàn dídi àtúnbí.

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọọkan tán.

**1.** Woli wo nínú Majẹmu titun ló lo odò Jordani fun baptism, tàbí ìwẹ̀numọ́?

**Matteu 3:1,5,6**

Ni ijọ wọnni ni __________ __________ wá, o nwaasu ni ijù Judea, Nigba naa li awọn ara Jerusalẹmu, ati gbogbo Judea, ati gbogbo ẹkùn apa Jordani yíká jade tọ̀ ọ wa, A si __________ wọn lọdọ rẹ̀ ni odò Jordani, nwọn njẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wọn.

Àkíyèsí: Ìtàn ihinrere bẹ̀rẹ̀, o sì tún pari pẹlu akori baptismu. Dájúdájú, eleyi jẹ́ kókó pàtàkì ninu ẹ̀kọ́ Jesu (Matteu 28:18,19).

**2.** Kíni ayẹyẹ ologo ti Bibeli to nsapẹrẹ "wiwẹ̀nù" kurò ninu àárùn ẹ̀ṣẹ̀?

**Işe Awọn Aposteli 22:16**

Njẹ nisinsinyi kini iwọ nduró de? dide, ki a si __________ rẹ, ki o si wẹ̀ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nù, ki o si maa pe orukọ Oluwa.

Àkíyèsí: Aṣẹ Bibeli nípa baptismu jẹ́ àpẹrẹ wiwẹ̀ ẹ̀ṣẹ̀ nù kúrò ninu ayé eniyàn, ki o si di atunbi.

**3.** Ni ibamu pẹlu Bibeli, iribọmi melo lo ṣe itẹwọgbà?

**Efesu 4:5**

Oluwa kan, ìgbàgbọ́ kan, __________ ______.

Àkíyèsí: O kéré tán, oniruuru ayẹyẹ marundilogun (15) ni a npè ni baptismu loni, ṣùgbọ́n ni ibamu pẹlu Bibeli, baptismu kan ló wà.

**4.** Kíni "baptismu" túmọ̀ sí?

**Kolosse 2:12**

Bi a ti ________ nyin pọ̀ pẹlu rẹ̀ ninu baptismu, ninu eyiti a si ti ji nyin dìde pẹlu rẹ̀, nipa ìgbàgbọ́ ninu iṣẹ́ Ọlọrun, ẹniti o ji i dìde kúrò ninu òkú.

Àkíyèsí: Ọ̀rọ̀ Giriki yi "baptiṣo" túmọ̀ sí "rírì bọ," "subú si ìṣàlẹ̀" tabi "kíkì bọ." Ènìyàn ko iti ṣe baptismu bi ki iṣe pé a ri iru ẹni bẹ́ẹ̀ bọ omi, tabi ki a sin in. Ọ̀rọ̀ yi "baptiṣo" ni a ma nlò ninu Bibeli lati tọka si ìyàsímímọ́ ti baptismu. Ọ̀rọ́ Giriki fun "wiwọ́n" tabi "dídà" ni a kò lò.

**5.** Jesu jẹ́ apẹrẹ wa, Bawo ni a ṣe baptisi Rẹ̀?

**Marku 1:9,10**

O si ṣe li ọjọ́ wọnni, Jesu jade wá lati Nasareti ti Galili, a si ti ọwọ́ Johannu baptisi rẹ̀ li odò Jordani, Lojukan náà bi o si ti ________ lati inú omi wá, o ri ọrun pínyà, Ẹmi nsọkalẹ bi àdàbà le e lórí.

Àkíyèsí: Johannu baptisi Jesu nipa rírì I bọmi ninu odò Jordani, ninu èyí ti Naamani ti gba iwẹ̀nùmọ́ kurò ninu ẹ̀tẹ̀. Kiyesi pé "nínú" Jordani ni (ki ise létí odò) ati pé Jesu "gògè wá" lati inú omi. Ìdí niyi ti Johannu fi nbaptisi ni "Aenoni léti Salimu, nitori odò pọ̀ nibẹ̀." Kristiẹni gbọdọ̀ tẹle apẹẹrẹ Jesu (1 Peteru 2:21), ẹniti O ṣe baptismu nípa wi wọ inu omi "lati mu gbogbo ododo sẹ." Matteu 3:15.



**6.** Bawo ni Filippi ṣe baptisi ìwọ̀fà Etiopia ?

**Iṣe Awọn Aposteli 8:38,39**

O si paṣẹ ki kẹ̀kẹ́ dúró jẹ́: awọn mejeji si __________ lọ sinu omi, ati Filippi ati iwẹfa; o si baptisi rẹ̀, Nigbati nwọn si __________ __________ ninu omi, Ẹmi Oluwa ta Filippi pá, iwẹfa kò si ri i mọ́: nitori ti o mbá ọ̀nà rẹ̀ lọ, o nyọ̀.

**7.** Òtítọ́ wo lo tun n sapẹẹrẹ niti baptismu ?

**Romu 6:4**

Njẹ a fi baptismu sinu ikú sin wa pọ̀ pẹlu rẹ̀: pé gẹ́gẹ́ bi a ti _____ Kristi ________ kúrò ninu òkú nipa ogo Baba bẹ́ẹ̀ni ki awa pẹlu ki o maa rin li ọ̀tun ìwà.

Àkíyèsí: Baptismu nsapẹẹrẹ ikú, ìsìnkú ati ajinde Kristi. A kọ́kọ́ kú sí ẹ̀ṣẹ̀, lẹhin náà ìsìnkú gbogbo igbé ayé ẹ̀ṣẹ̀ ninu omi, paríparí, ajinde kuro ninu omi sínú igbé ayé titun. Baptismu nipa iribọmi jẹ́ apẹẹrẹ pípé. Ìgbè ayé ẹ̀ṣẹ̀ a di kíkú, ẹni náà yio sẹmi nigbati a ba fẹ́ se baptismu fun un, yio sù gbalaja le ẹhin rẹ̀, titi ti gbogbo ara rẹ̀ yio fi wọ inu omi, ti omi yio si bò ó lórí, tabi sin in ninu omi. Lẹhin náà ni a o gbe ẹni naa sókè lati inu omi, yio si mi èémí titun gẹ́gẹ́ bi ọmọ titun, lati ma a gbé igbé ayé ọtun pátápátá, ti ise apẹẹrẹ ajinde. Kò si baptismu miran ti o tun yẹ apẹẹrẹ Bibeli yi. Awọn kan nsọ wípé, awọn npa ọjọ àìkú (Sunday) mọ́ lati bọ̀wọ̀ fun ọjọ́ ajinde, a ko darukọ èyí nínú Bibeli rárá.

**8.** Bawo ni baptismu se ṣe pàtàkì tó ?

**Marku 16:16**

Ẹniti o ba gbàgbọ̀, ti a ba si baptisi rẹ̀ yio ________; ṣùgbọ́n ẹniti kò ba gbàgbọ́ yio jẹbi.

**Johannu 3:5**

Jesu dahùn wípé, Lootọ, lootọ, lootọ ni mo wi fun ọ, Bikoṣepe a tún eniyàn bí, oun ________ le ri ijọba Ọlọrun.

Àkíyèsí: O dájú ninu Ìwé Mímọ́ pe baptismu jẹ́ dandan gẹ́gẹ́ bi o ti ṣe pàtàkì. Nitori idi èyí, bi baptismu ko ba ṣe e ṣe, gẹ́gẹ́ bi ti olè ori àgbélèbú, Jesu ti fun awọn bẹẹ ni ààyè fún baptismu ti Rẹ̀ (Matteu 3:15).

**9.** Ayẹyẹ tó ní ìbùkún wo ni a le fi wé baptismu?

**Galatia 3:27**

Nitori pé iye ẹnyin ti a ti baptisi sinu Kristi, ti _____ Kristi _____.

Àkíyèsí: Baptismu dabi ayẹyẹ ìgbéyàwó. Bibeli wípé, "Nitori Ẹlẹda rẹ li ọkọ rẹ; OLUWA awọn ọmọ-ogun li orukọ rẹ̀." Isaiah 54:5. Gẹ́gẹ́ bi obinrin se ma n jẹ́ orukọ ọkọ rẹ ninu igbeyàwó, bẹ́ẹ̀ni Kristiani n jẹ́ orukọ Kristi - lẹhin náà ni a n pè wọn ni Kristiani. Ayẹyẹ mejeeji yi gbọdọ̀ dúró lori ìfẹ́ ati iṣẹra-ẹni ki o to le e ni ìtumọ̀. Baptismu se pàtàkì ninu ayé Kristiani gẹ́gẹ́ bi ìyàwó ti ṣe pàtàkì ninu igbeyàwò.

**10.** Irú aṣẹ wo ni Jesu fifún àwọn ènìyàn Rẹ̀ ki o to gòkè lọ si ọrun?

**Matteu 28:19**

Nitori naa ẹ lọ, ẹ ma kọ́ orilẹ-èdè gbogbo, ki ẹ si ma ________ wọn li orukọ Baba, ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹ̀mí Mímọ́.



YOR-SP11.indd 1 12/7/12 9:01 AM

Àkíyèsí: Peteru tẹle aṣẹ yi ni ọjọ Pentekosti nigbati awọn eniyàn banujẹ nitori aisedeede wọn, "Ẹ ronipiwàdà, ki a si baptisi olukuluku nyin li orukọ Jesu Kristi." Iṣe Awọn Aposteli 2:38.

**11.** Kinni awọn amuyẹ Bibeli ti o gbọ́dọ̀ siwajú baptismu ?

A. Nini òye nipa ẹ̀kọ́ Jesu (Matteu 28:9,20).
B. Gba gbogbo ẹ̀kọ́ Jesu gbọ́ (Marku 16:16).
D. Ironupiwàdà awọn ẹ̀ṣẹ̀ to ti kọjá (Iṣe Awọn Aposteli 2:38).
E. Gbàgbọ́ pẹlu gbogbo ọkàn rẹ (iṣe Awọn Aposteli 8:37).
Ẹ. Gbígbà lati yipadà kurò ninu ẹ̀ṣẹ̀ (Luku 3:7,8; Romu 6:5,6).
F. Gba Jesu ni Olugbala rẹ, ki o si ni ìrírí atunbi (2 Korinti 5:17; Johannu 3:3,5).

Àkíyèsí: Niwọnba ìgbà to jẹ́ wípé ọmọ kékeré ko le tẹle awọn igbésẹ̀ òkè yi, kò ba Bibeli mu lati se baptismu fun ọmọde tító di ìgbà ti yio dàgbà lati ni òye ihinrere.

**12.** Nibo ni gbogbo ayédèrù baptismu ti sàn wá ?

**Marku 7:8**

Nitori ti ẹnyin fi ofin Ọlọrun si apakan, ẹnyin nfiyesi ________ atọwọdọwọ ti enìyàn, bi irú fífọ ohun-èlò ati ago: ati irú ohun miran pipọ bẹ̀ẹ̀ li ẹnyin nṣe.

Àkíyèsí: Baptismu nipa rírìbọmi nikan ni baptismu ti a ma nṣe ni ìgbà Bibeli ati fun ọpọlọpọ̀ ọdun lẹhin ikú ori agbelebú. Ṣùgbọ́n lẹhin náà, ni awọn aladabọwọ́ tun mu orisii baptismu miran wá, ti wọn wípé ki o le rọrùn fun wọn. Nipasẹ èyí ni baptismu mimọ́ Ọlọrun fi yipadà ati pé awọn àmì ọlọ̀rọ̀ rẹ tun farasin tí kò si ye ni mọ́.

**13.** Kinni Bibeli sọ nipa awọn ti wọn nfi ẹ̀kọ́ ènìyàn síwájú ododo Ọlọrun?

**Matteu 15:9**

Ṣùgbọ́n ________ ni nwọn ntẹriba fun mi, nwọn nfi ofin ________ kọni fun ẹ̀kọ́.

**Galatia 1:8**

Ṣùgbọ́n bi o ṣe awa ni, tabi angẹli kan lati ọrun wá, li o ba waasu ihinrere miran fun nyin ju eyiti a ti waasu fun nyin lọ, jẹ ki o di ẹni ________.

**14.** Ṣùgbọ́n ṣe ki ise baptismu ti Ẹ̀mí Mímọ́ lo rọ́pò baptismu ti iribọmi bí?

**Iṣe Awọn Aposteli 2:38**

Peteru si wi fun wọn pé, Ẹ ronipiwadà, ki a si baptisi ________ olukuluku nyin li orukọ Jesu Kristi fun idariji ẹ̀ṣẹ̀ nyin, ẹnyin o si gbà ẹ̀bùn ________ ________.

Àkíyèsí: Rárá! Se àkíyèsí ìgbà ti Peteru nwaasu ninú (Iṣe Awọn Aposteli 10:44-48), Ẹmi Mímọ́ ba le gbogbo awọn to ngbọ́ iwaasu náà, ọpọlọpọ awọn to jẹ́ wípé wọn ko iti ṣe baptismu. Bi o tilẹ̀ jẹ́ wípé wọn ti gba baptismu ti Ẹmi Mímọ́, Peteru tún wípé, wọn gbọdọ se baptismu ti iribọmi pẹlú.



**15.** Ṣe ó dára lati tún baptismu ṣe bí?

**Iṣe Awọn Aposteli 19:2-5**

O wi fun wọn pé, Ẹnyin ha gbà Ẹmi Mímọ́ naa nigbàtí ẹnyin gbàgbọ́? Nwọn si wi fun un pé, Awa kò gbọ́ rárá bi Ẹmi Mímọ́ kan wà, O si wípé, Njẹ́ baptismu wo li a ha baptisi nyin si? Nwọn sì wípé, Si baptismu ti Johannu, Paulu sì wípé, Nitootọ, ni Johannu fi baptismu ti ironupiwada baptisi, o nwi fun awọn eniyàn pé, ki nwọn ki o gbà ẹniti mbọ̀ lẹhin oun gbọ́, eyini ni Kristi Jesu, Nígbàtí nwọn si _____ , a ________ wọn li orukọ Jesu Oluwa.

Àkíyèsí: Ni ọjọ́ kan nigbàtí Paulu nwaasu ni Efesu, o ri awọn ọkunrin mejila (12) ti wọn ti ṣe baptismu nipaṣẹ Johannu baptisti, ti wọn ko iti gbọ́ nipa Ẹmi Mímọ́. Nigbati wọn gbọ́ irohin titun yi, wọn ṣe baptismu. Bẹ̀ẹ̀ pẹlu, bi ẹnikan ba ti sọ iriri Kristiani rẹ̀ nu, o gbọ́dọ̀ tun baptismu rẹ ṣe, ki iru ẹni bẹẹ le e padà si ọdọ Oluwa. Sise baptismu miran dára bi o ba jẹ́ wípé iru ẹni bẹ̀ẹ̀ ko iti se baptismu ni ọ̀nà tó ba Bibeli mu.

**16.** Njẹ́ siṣe baptismu ni ise pẹlu didarapọ̀ mọ ìjọ?

**Iṣe Awọn Aposteli 2:41**

Nitori naa awọn ti o si fi ayọ̀ gbà ọ̀rọ̀ rẹ̀ a baptisi wọn: li ọjọ́ naa a si ________ ìwọn ẹgbẹẹdogun ọkàn kún wọn.

**Iṣe Awọn Aposteli 2:47**

Nwọn nyin Ọlọrun, nwọn si ni ojurere lọdọ eniyàn gbogbo. Oluwa si nyàn kún ________ li ojoojumọ awọn ti a ngbàlà.

**Kolosse 3:15**

Ẹ si jẹ ki alaafia Ọlọrun ki o maa ṣe akoso ọkàn nyin, sinu eyiti a pè nyin pẹlu ninu ________ kan; ki ẹ si ma dupẹ́.

**Kolosse 1:18**

Oun si jẹ́ ori fun ara, eyini ni ________: ẹniti iṣe ipilẹṣẹ, akọbi lati inú òkú wá; pe, ninu ohun gbogbo ki oun ki o le ni ipò ti o ga julọ.

**1 Korinti 12:13**

Nitori pe ninu Ẹmi kan li a ti baptisi gbogbo wa sinu ara ________, iba ṣe Ju, tàbi Hellene, iba ṣe ẹrú, tabi ominira; a si ti mú gbogbo wa mu ninu Ẹmi kan.

Àkíyèsí: Ìwé Mímọ́ lọ tààrà ninu alaye rẹ, kò dojúrú rárá. Gbogbo eniyàn Ọlọrun ni a pè sinu ara kan, eyini ijọ, a ma n wọ inu rẹ nipasẹ̀ baptismu. Lẹhin ti a ba bi ọmọ, ọmọ titun naa gbọdọ wa lọdọ awọn obi rẹ fun ìtọ́jú, ààbò ati ìdàgbàsókè.

**17.** Bi mo ba kọ baptismu, ìmọ̀ràn tani mo n kọ̀ ?

**Luku 7:30**

Ṣùgbọ́n awọn farisi ati awọn amofin kọ ______ ________ fun ara wọn, a kò baptisi wọn lọdọ rẹ.

**18.** Nigbati Jesu ṣe baptismu, kinni Baba Rẹ̀ sọ?

**Marku 1:9,11**

O si ṣe li ọjọ́ wọnni, Jesu jade wá lati Nasareti ti Galili, a si ti ọwọ́ Johannu baptisi rẹ̀ li odò Jordani, Ohùn kan si ti ọrun wá, wípé, Iwọ ni ayanfẹ Ọmọ mi, ẹniti ______ mi ______ si gidigidi.

Àkíyèsí: Nigbàtí ọkan ninu awọn ọmọ Ọlọrun ba ronúpìwàdà ẹ̀ṣẹ̀ wọn ti wọn si ṣe baptismu, inu Ọlọrun ma ndùn.



# Èsì Rẹ

Njẹ́ o ṣetán lati bẹ̀rẹ̀ si i mura fun baptismu ti yio sọ ọ di mímọ́, èyítí yio mu ki Ọlọrun wípé, "Iwọ ni àyànfẹ́ ọmọ mi (ọkunrin tabi obinrin), ẹniti inu mi dun si gidigidi"?

ÌDÁHÙN:______________________

Bi o ba fẹ́ mọ̀ si i nipa baptismu, lọ ri Olusọagutan (pasitọ) tabi olori ìṣọ̀rí rẹ, ẹniti o se alaye ẹ̀kọ́ yi fun ọ, ki o si sọ ohun ti o fẹ́ fun wọn.

# Àfikún

Ipele yìí yio fun wa ni awọn ìròhìn kíkún lati tún kẹkọ síwájú.

## Apẹẹrẹ baptismu

Jesu ṣe baptismu ki iṣe nitori ti o nilò iwẹnumọ́ kúrò ninu ẹ̀ṣẹ̀, nitori ó jẹ́ alailẹ̀ṣẹ̀ (1 Peteru 2:22). Ìdí nìyí ti Johannu baptisi fi ní ìpòruru ọkan nígbàtí o ri Jesu to wá sí odò Jordani ti o sọ wípé ki Johannu se baptismu fún oun. Johannu wípé, "Emi li a ba baptisi lọ́dọ̀ rẹ, iwọ si tọ̀ mi wá?" Matteu 3:14.

Kí wa ni ìdí ti Jesu fi ṣe baptismu? A ní ìdí mẹta tó ṣe pàtàkì ti Jesu fi ṣe baptismu. Ikinni, Jesu ṣe baptismu nitori awọn ti wọn kò le e ṣe baptismu funrara wọn. Nígbà miran ti o le jẹ́ wípé awọn ènìyàn wà ninu ọgbà ẹ̀wọn tabi ile-ìwòsàn, awọn akokò yi ko fun wọn ni anfani lati ṣe baptismu. Jesu fun wọn ni ààyè nipaṣẹ baptismu ti Rẹ̀. Olè ori agbelebu jẹ apẹẹrẹ kan (Luku 23:43 ). Ekeji, Jesu ṣe baptismu fún apẹẹrẹ, ki awa náà le e maa tọ ipasẹ Rẹ̀ (1 Peteru 2:21). Ẹkẹta, Jesu ṣe baptismu, kí awa pẹlu nipa wiwo ìrírí Rẹ̀, ki a le mọ̀ ohun ti a o maa retí nipa ìgbàgbọ́.

Lati ṣe àlàyé, ẹ jẹ ki a mu awọn ẹṣẹ yi ní ọ̀rọ̀ lé orí ọ̀rọ̀, ki a le mọ ohun ti a o maa retí ninu baptismu wa. Matteu 3:16 ati 17 sọ wípé: "Nigbati a si baptisi Jesu tán, o jade lẹsẹkan náà lati inú omi wá: sì wò ó, ọrun ṣí silẹ̀ fun un, o sì rí Ẹmi Ọlọrun sọkalẹ̀ bi àdàbà, o si bà le e: Si kiyesi i, ohùn kan lati ọrun wá, nwipe, Èyí ni àyànfẹ́ Ọmọ mi, ẹniti inu mi dùn si gidigidi.

| | | |
|---|---|---|
| "Ọrun sí silẹ̀" | = | A gba anfaaní lati de ọ̀dọ̀ Ọlọrun. |
| "Ó rí" | = | Ojú ẹ̀mí wa ti là, o fun wa ni ìmọ̀ ati oye titun. |
| "Ẹ̀mí Ọlọrun" | = | A mọ bi O se ndarí wa. |
| "Sọkalẹ̀ bi àdàbà" | = | Alaafia rọra wọ inu ayé wa. |
| "Ohùn kan lati ọrun" | = | A o bẹ̀rẹ̀ si igbọ́ ohùn jẹ́jẹ́ kekere. |
| "Àyànfẹ́ ọmọ mi" | = | A sọ wa di ọmọ ninu idile-ọba Rẹ̀, a di ọmọ orilẹ̀-èdè oniruuru. |
| "Inú mi dùn gidigidi" | = | Ọlọrun gbà wá, O si dariji wá pátápátá. |

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP11.indd 2 12/7/12 9:01 AM